# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

NO 864 SATURDAY DECEMBER 5, 1964 (2D


## Obinrin Kan To Ti Ku Tun Pada S'aiye

GLASGOW:- Ni ana ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni Irohin de ọwọ wa lati ọwọ oniwe Irohin wa lati Glasgow pe Obinrin kan ti gbogbo enia ti gba pe o ti ku ni a tun gi ọ pe o pad di alaye lẹhin ti nwọn ti gbe oku rẹ de ile iwosan ti awọn lakulaku eyi to je pe ko ku mọ.

Obinrin na ni iyaafin Catherine Leas- s' ẹni ọdun marundinlogoji ni a ti gbọ tẹlẹ pe o ti ku ni ile iwosan kan ti a npe ni Glasgow *Royal* Infirmary. Irohin na tun fi ye wa pe nigbati mọto ti nwọn fi gbe oku gbe oku obinrin na ce ile iwo- san lakulaku ni awọn Dokita to wa ni ile iwosan na mọ pe obinrin na ko ti iku ati pe o nmi diẹdie.

Oniwe irohin wa to wa ni ile iwosan na fi ye wa pe lehin ti awọn Dokita to wa ni ile iwosan lakulaku na ri pe obinrin na ko ku rara ni nwọn yara tete lo ẹrọ *kan* ti o wa ni ile iwosan na ti o nfi atẹgun si ara enia ni nwọn yara lo ti nwọn si fẹ nfẹ ategun na si lara lati fi han pe iyaafin Lea*sk* ko ku rara, eyi ti nwọn yara nṣe tọju rẹ ni ile iwosan na.

# EGBẸ AFẸNIFẸRE FẸ PE IJỌBA IBILẸ OGBOMỌSHO L'ẸJỌ

**IBADAN:— Ni ọjọ Eti ti ise ọjọ kẹrin osu yi ni irohin de ọwọ wa lati ọwọ Oludamọran lori eto ofin fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Naijiria Alhaji Busari Obisẹsan pe ẹ bẹ Afẹnifẹre yio pe igbimọ Afuuishọ ti Ijọba ibilẹ ti ilu Ogbomoshọ eyi ti ẹgbẹ Dẹmọ NNDP nse akoso rẹ lẹjọ lori eto ofin titun ti ijọba ibil na se laipẹ yi pe ko si enia kan to gbod rin ni ilu Ogbomọshọ larin agogo mẹwa alẹ titi di agogo mẹfa owurọ ọjọ keji ati pe ko si Alejo kan to gbọdọ wo ilu Ogbomosho laijẹ pe o ti fi ara han fun awon Alakoso Ijoba ibilẹ ilu na**

Ninu Irohin to ti ọwọ Alhaji Obisẹsan jade na ni o ti se alaye pe on ti fi ọrọ na sun Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji D. S. Ade- gbenro ati igbimọ ti ndari iṣẹ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naiji- ria UPGA pe ti Minista Alamojuto eto Ijọba ibilẹ ti Ijọba ipinlẹ Iwọ orun ba fi ọwọ si iru ofin bayi o ni nwọn yio gbe lọ si ile ẹjọ.

Alhaji Obisesan tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe Ofin ti Ijọba Ibilẹ Ogbomọ- shọ na ṣe ko tọna rara ati pe ko ba ofin lọ biko ṣe pe nwọn tun lodi si ofin eto ilẹ wa ati paapa julọ pe o tun je ofin ti ko ba eto ofin ilẹ Naijiria lọ Alhaji Obisẹsan tun se alaye ninu ọrọ rẹ pe nṣe ni Ijọba Ibilẹ ilu Ogbomọshọ paapa tun lu ofin ilẹ Naijiria lori ofin ti ko tọna ti nwon ṣe na

Alhaji Obisesan tun ṣe alaye pe eto ofin ti Ijọba ibilẹ na ṣe ko tọna ati pe gbogbo enia ilẹ Naijiria lo ni ẹtọ lati rin gẹgẹbi o ṣe wu ni ilẹ Naijiria ati pe ko si ọmọ ilẹ Naijiria kan ti ko le lọ si ilu to ba wu ni Naijiria laisi pe awọn enia kan nfẹ fi iya jẹ.

Alhaji Busari Obiṣẹsan tun ṣe alaye pe on mọ daju pe ẹgbẹ Dẹmọ NNDP ti nse akoso Ijọba Ibilẹ ilu Ogbomọshọ lo rlo eto ofin ti ko tọna eyi ti nwọn fẹ gbe jade na. Alhaji Obi- sẹsan tun se alaye pe igba- ti nwọn ti m pe awọn enia ilu Ogbomọsho ti ṣe ileri ọka wọn pe awọn ko ni dibo fun ẹgbẹ Dẹmọ N. N D. P. eyi ti Oloye S. L. Akintọla iṣe olori wọn ati pe awọn enia ilu na ti sọ pe awọn koni dibo fun ẹgbẹ na lo mu awọn ọmọ ile igbimọ Afunsho ti ijọba ibilẹ ilu Ogbomọshọ ṣe eto ofin ti ko tọna.

Irohin na tun fi ye wa pe awọn ọmọ ilu Ogbomọshọ ti ṣe ileri pe awọn ko ni dibo fun ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ sNNDP ti wọn ba le mu sile ni ilu Ogbomọsh lasi ko idibo to mbọ yi.



OLOYE S. L. AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Alhaji Obiṣẹsan so pe Ọgbẹni Victor Lajide ni iṣe Alaga Ijọba ibilẹ na ati pe o ya on lẹnu lati ri pe Ijọba ibilẹ na nṣe eto ofin ti ko tọna rara.

Siwaju si Alhaji Obiṣẹsan tun se alaye pe ile ẹjọ ti mọ nipa eto ofin ni yio ba wọn ba eto ti ko mu ọgbọn lọwọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ogbomọshọ na nṣe lati fi idi awọn ọmọ ipinlẹ Iwọ orun lọwọ lati rin gẹgẹbi awọn ṣe fẹ.

Ninu irohin kan ti o jade lati ọwọ ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti ipinlẹ Iwọ orun ni nwọn ti ṣe alaye ninu ọrọ wọn pe ofin buburu ti ẹgbẹ ti Oloye Akintọla nṣe ayi ni gẹgẹbi nwọn yio ṣe le ṣe ki wọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu miran ma le ri aye lati lọ ṣe ipade pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ wọn.

Ninu Irohin ti o de ọwọ wa lati owọ ẹgbẹ ọdọ Afẹ- nifẹre na ni nwọn ti ṣe ala- ye pe eleyi jẹ ohun itiju lati ri pe ni ilu Olotu Ijọba Ipinlẹ kan ni yio ti ma jaya ẹgbẹ oṣelu ti o jẹ Alatako si ẹgbẹ rẹ eyi to jẹ pe ilu Olotu Ijọba na lo yẹ ki o je ibikan ti o lagbara ju ti ẹgbẹ ni lati ni awọn enia ti yio wa lẹhin ẹgbẹ rẹ eyi to jẹ pe nṣe loyẹ ki o ma sọ pe on gbẹyẹ kan to pọ dada ni ilu to jẹ tirẹ

Awọn ẹgbẹ ọdọ Afẹnfẹre na tun sọ ninu Irohin wọn pe awọn nfẹ fi ye awọn enia ilu Ogbomọshọ ati ilu mi- ran lati pe ẹgbẹ wọn fẹ mu wọn kuro ninu okunkun ti ẹgbẹ Dẹmọ fi wọn si ati pe ki nwọn pada si oju imọlẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe



OLOYE AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

alaye pe nigbati awọn ẹgbẹ Dẹmọ NNDP ti nwọn je Alatako wọn ko fun wọn la ye lati polowo Ibo lati ile kan si ile kan awọn ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹrẹ na sọ pe awọn fi gbogbo na sile fun awọn Adib lati fun ara mu mu

WO OJU EWE KẸFA


**UPGA Flag Now Ready**

FLY UPGA FLAG FOR UNITY, PROGRESS, PROSPERITY & STABILITY
OBTAINABLE AT UPGA BUREAU OF PUBLICITY & INFORMATION
2 NNMADI AZIKIWE STREET, LAGOS
PHONE: 24381 & 22637
PRICES: CAR SIZE 6/- LARGE SIZE 35/
LIMITED QUANTITY AVAILABLE

# Awolọwọ Dorisa (Apa 7)

### Lati ọwo Adio Mosanya

fi jagun yi bi ogun Hastings. Iwe ati apoti ibo didi l' eo fi jagun na. Nitorina o yẹ ki awọn olufokansin ma sọ.a ki nwọn si na gbad.ra.

Ma gbadura ni kọrọ yara re b alagẹmọ. Bi gbatii Josua mta awọn ara Ameleki ja; Mose, Aaroni ati Huru gun oke sinai lo, nwọn si gbe ọwọ wọn soke Olorun fun ebẹ. Josua si şẹgun. Bẹna ni Awolọwọ yio si şegun lagbara Ọlọrun ati pẹlu atilẹhin awọn enia. Awọn ota Awolọwọ ko da nkankan şe ri, nwọn ki ronu ohun ti mbọ, nwọn ko damọran ohun kan r i nwọn ko ni eto ohun kan, bẹni nwọn ko si dara fun nkan. Nwọn ko ni ohun ti o le mu awọn mekunu suru bo wọn. Nwọn bajẹ bi ibẹpe ti o ti pọn bajẹ.



Oloye Ọbafẹmi Awolowo

NA AMA PON OLODODO LE

Arẹ Akan nse ilẹ Naijiria wa yi Şugbọn ko si aisan ti kosi Iwosan fun Awolọwọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre lejiya nwọn ledi ẹni pipa gẹgẹbi nitori ajọ mo N. C. N. C pẹlu N P C ati ẹgbẹ Pi Pi Pi Ite ise ibi yi ko je gbe wọn ga nitoripe nwọn ko mo ọna Ilọs'waju Nipo tifi iya jẹ Awolowo nwọn tubọ gbe ga ni Ẹniti o ba jiya fun otitọ ati eto yio di ẹ i nla ati orisa akunlẹbọ Kini ọn o enia tun sẹ da l aye yi Bi asiki Awo temi tinga si beena ni ti awọn ọta rẹ dinku

IKABO-SEGUN KU IKỌ ORO

Lati igbati ati fi ọtẹsi Ijẹba sun Awolọwọ Ọpọlọpọ okan lo ti sẹlẹ Eyiti o bẹru ju ni ika oro ti Arẹ-.ọ Awolọwọ Şegun Awọlowọ Agbẹjọro ati omowe oloye giga nibu ofin ku lojiji Ijamba mọto ayọkẹlẹ lopa Şẹgun lọna Ibadan si Ikorodu ni ọjọ kẹwa osu keje ni odun 1963

Aiyọ ni Ọpọlọpọ enia lo ti nku ni Naijiria sugbọn ikanu awọn enia fun iku Şeguo ko l'ẹgbe. Awọn enia ke ni gbaba titi, waya to bọ si ipo Awolọwọ ko l'onka.

"Şugbọn asiko ti a şe isẹ bubnru ki dara rara, a ko si mọ ara wa." Awọn ọmọ Yoruba ti ode oni ni ọna ti nwọn ngba san ore fun Olore ati atọkun wọn eyi na ni nipa gbigba ojulowo ọmọ wọn lọwọ wọn, Arẹmọ Herbert Macaulay ku ni ọdun 1931 ni ọjọ ti a şi gada Carter nitoripe awọn ire awọn enia rẹ ti şe Yoruba.

Loni, oruko wo ni a so popo ti o wa ni isalẹ gada Carter nibiti ọmọ Herbert Macaulay ku si? Nnamdi Azikiwe Road ni dipo Victoria Street, ti a mọ tẹlẹ Awọn Yoruba şe alaimore tobẹ gẹ si Herbert Macaulay ti nwọn jẹki ile rẹ ti a npe ni "Kirksten Hal" wa di ọrọ itan

Bọya ayanmọ Şẹgun lo jẹki o ku l'ọmọde. Şugbọn bi Şẹgun Awolọwọ ba baba rẹ ni ipo ti o yẹ, boya ki ba tt ku nigbati o ku eyi mu mi ranti igba woli Hesikaya. Ọlọrun ran woli si Hesikaya lati sọ fun pe o ni lati ku lasiko kan. Hesikaya si gbadura si Ọlọrun, o si şanu rẹ. O si ran woli na pada lati so fun wole Hesikaya pe On ti dari ji ati pe on ti fi kun ọjọ aiye rẹ, Ki Oluwa fi ọrun ke Şegun; Amin

Nigbẹnhin, ọjọ ti a reti de. Işẹle ti a ko mọ ibi ti yio ja si ẹgẹbi ọrọ as tẹlẹ 'Tony Enahoro Olohun yo wa d eiu rẹ ni ọjọ Abamẹta ọjọ keje ni ọşu kẹsan ọdun 1963 nigbati Adajọ S. O. Lambo ff To y si ẹwọn ọdun mẹdogun. Payi ni Oloye Anthony Eronsele Enahoro Igbakeji olori Egbẹ fẹnifẹre wa dabira bayi:- O lọ s'ẹwọn lẹmẹta nigbati o nja fun ominira On ni ẹgbẹ Afẹnifere yan lati bere fun ominira. ilẹ ninu ile Igbimọ Aşofin ti aparọ ni ilu Eko ni ọdun 1953. On si ni ẹni kinni ninu awọn ti a fi ẹsun kan ti a ko şe.

idaju fun. Idajọ nla wa da ni ọjọ kọkanla oşu kẹsan ọdun 1968. Ọlọla Adajọ George Sodeinde Sowemimọ Oloye Asalu Ọba ni Abẹokuta lo sọ pe Awolọwọ jẹbi ẹsun na, o si fi dajọ ẹwọn ọdun mẹwa fun Mo gbọ ikede na bi Peteru se gbọ akuko lẹhin ti o sẹ Jesu Kirist lẹmẹta. Gẹgẹbi Peteru şe ranti asotẹlẹ Oluwa rẹ, bẹna n emi na ranti asọtẹlẹ Ogbẹni Yoruba kan ti ọjọ kandinlogbọn oşu karun ni ọdun 1962 ti o sọ bayi pe: Mo sokun, ki şe bi awọn obirin Jerusalẹm şe sokun fun Jesu, şugbọn fun ohun alẹbi ti awọn enia mi fi ẹnu wọn sọ. Adupẹ pe isọtẹlẹ na ki şe lati ọdo Olọrun; ati ọdọ elẹran ara ni o ti wa. Ni osiko ti a gb'ogun ti wa. Ni asiko ti a gb'ogun ti Azikiwe ni ọdun 1958, akpara ọmọ Yoruba kan lo ni posi Dokita Mbadiwe lo si Ikoyi bi ẹni pe awọn ti lo sinoku Mbadiwe nipa ọrọ isẹlu. Ese awọn enia mi ti kigbe de ọrun. Ojo kẹrin ọsẹ ni şusun ku. Ojo kẹrin ọsẹ na ni b qa Şẹd' ero ẹwọn. A ...ọ ri bẹ nigbamira. Bi ya ola ba gbe ni şalẹ, kekere a ma gb'or Oluwa rẹ ni ọjọ kanna. Talo fe sọ se wipe ọjọ dada ni ọjọ kẹrin ọsẹ ?

Napeen loso bayi pe ojo kan soso eba igbesi aiye omo enia jẹ Pẹlu wahala todeba Awolowo gbogbo ogo ati ola Yoruba koda bi osepe ẹniti o-ito naẹmo anjoti wo Aini lati so otito nipa Be ehebu tikalararẹ Diẹ ninu awon Yoruba ti ba awọn gan se igbimọ lati se ibi fun awọn enia won Şugbon nigbati asiko ba to esin awon arope ise rere lori yio aitu si igbagba awon to pẹlu awon merindorin ti o lo bura pe awon duro ti Awoọlwọ ti nwọn sẹhin lati bosi ode Akintọla ẹbi gbogbo ohun ti ode Yoruba loni wa lori nwo bi won ba duro ti Awolọwọ de opin, ilẹ Yoruba ki ba ti di rudurudu bayi. ọrukọ rere san ju wura ati fadaka lọ, Igbesi aiye rere ti ko to nkan san ju ọpọlọpọ iwe ti ko wu lo.


## Aiye Tọto African Healing Home

Bere ogun itaja Ti o daju Ti a şe ni Turari pẹlu lọfinda. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Irohin ko to Afojuba orişirişi aruu ati ilọsiwaju

Lẹnu işẹpẹlu Ajẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ w

Office
7. Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin

# Awolọwọ Dorisa (Apa 7)

### Lati ọwo Adio Mosanya

fi jagun yi bi ogun Hastings. Iwe ati apoti ibo didi l' wo fi jagun na. Nitorina o yẹ ki awọn olufokansin ma sọ a ki nwọn si na gbad ra.

Ma gbadura ni kọrọ yara re b alagẹmọ. Bi gbatii Josua mta awọn ara Ameleki ja; Mose, Aaroni ati Huru gun oke sinai lo, nwọn si gbe ọwọ wọn soke Olorun fun ebẹ. Josua si ṣẹgun. Bẹna ni Awolọwọ yio si ṣegun lagbara Ọlọrun ati pẹlu atilẹhin awọn enia. Awọn ọta Awolọwọ ko da nkankan ṣe ri, nwọn ki ronu ohun ti mbọ, nwọn ko damọran ohun kan r i nwọn ko ni eto hun kan, bẹni nwọn ko si dara fun nkan. Nwọn ko n ohun ti o le mu awọn mekunu suru bo wọn, Nwọn bajẹ bi ibẹpẹ ti o ti pọn bajẹ.



Oloye Ọbafẹmi Awolowo

NA AMA PON OLODODO LE

Arẹ Akan nse ilẹ Naijiria wa yi Ṣugbọn ko si aisan ti kosi Iwosan fun Awolọwọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre lejiya nwọn ledi ẹni pipa gẹgẹbi nitori ajo mo N. C. N. C pẹlu N P C ati ẹgbẹ Pi Pi Pi Ire ise ibi yi ko je gbe wọn ga nitoripe nwọn ko mo ọna Ilọs'waju Nipa titi iya jẹ Awolowo nwọn tubọ gbe ga ni Ẹniti o ba jiya fun otitọ ati eto fio di ẹ i n/a ati orisa akunlẹbọ Kini ọn o enia tun sẹ da l aye yi Bi asiki Awo temi tinga si beena ni ti awọn ọta rẹ dinku

IKABO-SẸGUN KU IKO ORO

Lati igbati ati fi ọtẹsi Ijoba sun Awolowọ Ọpọlọpọ okan lo ti sele Eyiti o beru ju ni ika oro ti Arẹ- o Awolowo Ṣegun Awolowọ Agbẹjọro ati omowe oloye gige ninu ofin ku lojiji ijamba moto ayọkẹlẹ lọpa Ṣẹgun lona Ibadan si Ikorodu ni ojọ kẹwa osu keje ni odun 1963

Aiyẹ ni Ọpọlọpọ enia lo ti nku ni Naijiria sugbọn ikenu awọn enia fun iku Ṣẹgun ko l'egbe. Awọn enia ke ni gbaba titi, waya to bọ si Ipo Awolọwọ ko l'onka.

"Ṣugbọn asiko ti a ṣe iṣẹ bubnru ki dara rara, a ko si mọ ara wa." Awọn ọmọ Yoruba ti ode oni ni ọna ti nwọn ngba san ore fun Olore ati atọkun wọn eyi na ni nipa gbigba ojulowo ọmọ wọn lọwọ wọn, Arẹmọ Herbert Macaulay ku ni ọdun 1931 ni ọjọ ti a gi gada Carter nitoripe awọn ire awọn eni rẹ ti se Yoruba.

Loni. oruko wo ni a so popo ti o wa ni isalẹ gada Carter nibiti ọmọ Herbert Macaulay ku si? Nnamdi Azikiwe Road ni dipo Victoria Street, ti a mọ tẹlẹ Awọn Yoruba ṣe alaimore tobẹ gẹ si Herbert Macaulay ti nwọn jẹki ile rẹ ti a npe ni 'Kirksteo Hal" wa di ọrọ itan

Bọya ayanmọ Ṣẹgun lo jẹki o ku l'ọmọde. Ṣugbọn bi Ṣ ẹ g u n Awolọwọ ba baba rẹ ni ipo ti o yẹ, boya ki ba tt ku nigbati o ku eyi mu mi ranti igba woli Hesikaya. Ọlọrun ran woli si Hesikaya lati sọ fun pe o ni lati ku laskọ kan. Hesikaya si gbadura si Ọlọrun, o si ṣanu rẹ. O si ran woli na pade lati so fun wole Hesikaya pe On ti dari ji ati pe on ti fi kun ọjọ aiye rẹ, Ki Oluwa fi orun ke Ṣegun; Amin

Nigbẹnhin, ọjọ ti a reti de. Iṣẹle ti a ko mọ ibiti yio ja si ẹgẹbi ọrọ as tẹlẹ 'Tony Enahoro Olohun yo wa d eju rẹ ni ọjọ Abamẹta ọjọ keje ni ọṣu kẹsan ọdun 1963 nigbati Adajọ S. C. Lambo ff To y si ẹwọn ọdun mẹdogun. Bayi ni Oloye Anthony Eronsele Enahoro Igbakeji olori Ẹgbẹ fẹnifẹre wa dabira bayi:- O lọ s'ewọn lẹmẹta nigbati o nja fun ominira On ni ẹgbẹ Afẹnifere yan lati bere fun ominira. ilẹ ninu ile Igbimọ Aṣofin ti apapọ ni ilu Eko ni ọdun 1953. On si ni ẹni kinni ninu awọn ti a fi ẹsun kan ti a ko ṣe. idaju fun. Idajọ nla wa da ni ọjọ kọkanla oṣu kẹsan ọdun 1968. Olọla Adajọ George Sodẹinde Sowemimọ Ol ye Asalu Ọba ni Abẹokuta lo sọ pe Awolọwọ jẹbi ẹsun na, o si fi dajọ ẹwọn ọdun mẹwa fun Mo gbọ ikede na bi Peteru se gbọ akuko lẹhin ti o sẹ Jesu Kirist lẹmẹta. Gẹgẹbi Peteru ṣe ranti asotẹlẹ Oluwa rẹ, bẹna ni emi na ranti asọtẹlẹ Ogbẹni Yoruba kan ti ọjọ kandinlogbọn oṣu karun ni ọdun 1962 ti o sọ bayi pe: Mo sokun, ki ṣe bi awọn obirin Jerusalẹm ṣe sokun fun Jesu, ṣugbọn fun ohun alẹbi ti awọn enia mi fi ẹnu wọn sọ. Adupẹ pe isọtẹlẹ na ki ṣe lati ọdo Olorun; ati ọdọ elẹran ara ni o ti wa. Ni osiko ti a gb'ogun ti wa. Ni asiko ti a gb'ogun ti Azikiwe ni ọdun 1958, alapara ọmọ Yoruba kan lo ni posi Dokita Mbadiwe lo si Ikoyi bi ẹni pe awọn ti lo sinoku Mbadiwe nipa ọrọ iṣelu. Eṣe awọn enia mi ti kigbe de orun. Ọjọ kẹrin ọsẹ ni ṣuun ku. Ojo kẹrin ọsẹ na ni b qa Ṣẹd' eto ẹw n. A ...ọ ri bẹ nigbamiran. Bi ya ola ba gi e ni ṣa lẹ, kekere a ma gb'or Oluwa rẹ ni ọjọ kanna. Talo fe sọ so wipe ọjọ dada ni ọjọ kẹrin ọsẹ ?

Napeon loso bayi pe ojo kan soso eba igbesi aye omo enia jẹ Pẹlu wahala todeba Awolowo gbogbo ogo ati ola Yoruba koda bi osepe ẹniti o-ito naẹmo anjoti wo Aiyi lati so otito nipa Be ehebu tikalarare Diẹ ninu awon Yoruba ti ba awọn gan se igbimọ lati se ibi fun awọn enia won Ṣugbon nigbati asiko ba to esin awon arope ise rere lori yio aitu si igbagba awon to pẹlu awon merindorin ti o lo bura pe awon duro ti Awọlwọ ti nwọn sẹhin lati bosi ọdẹ Akintọla ẹbi gbogbo ohun ti ode Yoruba loni wa lori nwo bi won ba duro ti Awolọwọ de opin, ilẹ Yoruba ki ba ti di rudurudu bayi. orukọ rere san ju wura ati fadaka lọ, Igbesi aiye rere ti ko to nkan san ju ọpọlọpọ iwe ti ko wu lo.


**Aiye Tọto African Healing Home**

Bere ogun itaja Ti o daju Ti a ṣe ni Turari pẹlu lọfinda. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Irohin ko to Afojuba orişirişi aruu ati ilọsiwaju
Lẹnu iṣẹpẹlu Ajẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ w

Office
7. Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin

# Ẹnyin Ọmọ Igbomina Ewo Li Ẹ Ṣe ?

Lati ọwọ Samuel Ogunṣọla Ọmọ Ilu Esle.

Mo juba Edumare, mo juba araiye, Nigbati ekolo njuba ilẹ ni ilẹ ṣe nlanu fun, Igi ko nda li oko, ki o pa ara ile bẹni aja ko nyin ni yẹwu ko pa ero ọna. Ẹnyin ọmọ Igbomina ẹ jẹki imọ wa ṣe ọkan, Baba La yinka mbẹ nilẹ ti o, nwo wa leju, ejeki a gbe e dide, O wc awọn baba wa kan sọ wipe, bi igi ba da ti ori rẹ ni a kọkọ ngbe kuro Ẹjẹki a dide a gbaradi ki a dibo fun Awolowọ, bi o ba wọle, o daju pe gbogbo ohun ti a fẹ ni yio tẹ wa lọrun.

Ẹnyin ọmọ Igbomina ẹ ṣe suru, oju ni yio ti eke Ẹ jẹki a dide bi enia kan, ki a dibo fun ẹgbẹ Awolọwọ wọ le Mu ọkan rẹ le kini iwọ mbẹru nigbati iwọ ko ṣe eke ọrọ mi oni dori ko dori Alaṣeju Alaṣetẹ

Ọkunrin kan wa, ko ni ga ko ni go a wa ri owo bi ada ta pọuuu lo o wa bere si rọ kini on yio fi owo yi ṣe o berẹ si fi ra Awo afe panu ati oriṣirisi nkan hawọn in o tun wa nronu kili on yio ti ṣe awọn awo ti on ra nwọnyi ngbero lati ta bi on ba ta a on yio jere adọta pọun miran owo on yio di ọgọrun pọun

O wa gbero lati fẹ ọmọ'a kan ati Talika kan Bi ọmọ ba ba se onjẹ on ko ni jẹ sugbọn on yio jẹ ti ọmọ, Talaka bi Iya ọmọba tabi oba paapa ba kunlẹ fun on ọn yio gba li eti on yio si ta nipa koitipari.

## YE IRAWỌ RE WO

AQUAIUS (Jau. 22 Feb. 20) Ọrọ nipa awọn ẹbi rẹ yio mu ọ binu loni ṣugbọn ayọ ni igbẹhin rẹ ni aṣalẹ,

ARIS (Mas. 21 April 20 Lati ọsan ọjọ oni, ire yo bẹrẹ lori rẹ ọrọ nipa ẹgbẹ yio mu ọ gbayi sọra rẹ nipa fifi aju si ọna daradara loni.

TAULUS )April 31 May. 20) Mase gbẹkẹle eni a pupọ ki oni ma ba jẹ ọjọ ẹsun, o dara ki o nfẹ si awọn olufẹ rẹ osisẹ kan ti yio si baya fun ọ yio jẹ ki inu rẹ mọ si enia.

GEMINI (May. 21 June. 21) Nkan yani kan yio de si ọ nipa ọrọ ara rẹ mase fi ọrọ na sire o nitoripe diẹ diẹ iwọ yio gba ibẹ di olokiki.

CANCER (J ue 22 July) Iwọ yio ri iranlọwọ gba lati ẹdọ awọn ara lọwọ wa lati fi tun nkan ti o wa ṣe gbogbo ija ti o wa nilẹ ni iwọ o fi opin si asalẹ yio gbadun

LEO (July. 23 Aaig 23) Iwọ yio gbalejo kau ti yio tọ ọ wa fun anu rẹ iranlọwọ fun alsini, ni ṣiṣẹ bẹ ọpọ ohun ti o ru ọ loju ha iwọ yio ri paiya.

VIRGO (Aug. 24 Sept. 23 Maṣe ṣe fari pupo wipe gẹdegbe li o wa. Masc gbe ara rẹ ga akoko rẹ nfẹ ayipada, lọ ke si ọrẹ rẹ.

LIBRA Sept. (24 Oct. 23) Ṣe ohun ti o jẹ wipe awọn ọrẹ rẹ yio fi ma ta ọ mọra papaa ninu ile rẹ abawọ yio wa mbẹ ẹrọ di ọwọ rẹ.

SCORPIO (Oct. 24 Nov. 22) Iwọ yio kọwe kan loni ti yio mu itẹ lọrun wa ba ọ iwọ yio si ri alejo abami kan ni aṣalẹ oni.

SAGITARIUS (Nov. 23 Dec. 21) Se gbogbo nkan gẹgẹbi o ti tọ ati bi o ti ye, ki o si ṣe e ni eto igbehin re yio si ya o lenu. iwọ ṣorire lọdo obinrin, ati nipa owo

CAPRICORN Dec. 22 Jane 21 Ọna kọna ti o ba te ọ lowo loni ki o mu dari re pelupelu, bi nmọn ba fi iwe pọọ si ibi ere. Bi o ba ta teto loui ire mbẹ fun ọ sugbọn mase biuu koje ala,


## Bọ Lọwẹ Oso Ati Aje

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutu ṣiṣe pẹlu Iwe ṣan 20/- mejila £2 5/
Iwe Egbogi Awogba Arun 22/- meji 40-
Turari isẹgun Ajẹ, Oṣo ati awọn aba tẹnijẹ O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/6- pakẹti 2/
Ki ṣe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn ọja yi aabo ti o nipọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ
Fi owo ranṣẹ si

J.O. ,HOYINKA
11 Alaba Street
Oduaborẹ Mushin.

## Ipolowo Ọja Rẹ Ko T Yege

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ
SINU
**IROHIN IMỌLẸ**

T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
ADVRTISMENT MANAGER

**IROHIN IMỌLE**
16, Bamgbose Street Phone 21985

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA
## „DYNAMIREN" TỌNIK

AE-BI-ALE Egbogi tọniki Ja manu titun ti kbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbid an iṣẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ko ba ṣiṣẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja ọgbọn ọdun o si de adọrin tab ubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ vio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyẹn bẹ.



Bere egbogi na ni Ṣọbu:
NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos. Nigeria.
ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI

Aworan ẹgbẹ yi fihan gban gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ wa ni ara rẹ ti nyọọ lẹnu nigbagbogbo. Iṣẹ ni anpe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngba ṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si soro pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.



CYCLOVEN

Ọpọlọpọ egbogi ni o wa ti a nta kakiri ode nisisiyi ti nwọn ma a npolowo nwọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya ni a le i ri mẹwa ninu awọn ẹun ti o leṣe iwosan arun Ai daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn gbe lọ si ile iwosan lati lọ ge eyiti o ba nyọ jade omusu ku nipa be awọn o bọ lọwọ rẹ patpaata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyonu rẹ vio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwu ẹran Ṣuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ sode ninu omuṣu tabi ti o ba ninu ẹjẹ walẹhin igbọnsẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ati awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si danwọ kuaju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de ba ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo awọn ti a tanigboro Naijiria bere ni :

NIGERIA MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos



# Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọ ọkan ẹhin didun ibadi wiwo tabi sisan ẹjẹduu ati tabi aikoto ẹjẹ ara Inu gbigbona nigbakugbo Igba- -aiye riro ọmu riro didun arẹ atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun ara ẹṣẹ ara sisan ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itoju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma ayọ wọn lẹnu ni iru nigbakugba pẹlu

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI AJỌ WỌN NPENI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba laila ki awọn Orişiriş robirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to da awọn agbalagba aiye atijọ mn ati wipe ko si ohun ti ale fi iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti aiperi n yọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọn eti riro tabi se iwosan iyọnnu apo-ile-ito egbogi oju didun tabi ni ọna-ọfun didun, ati orişirişi omiran pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn:-

NIGERIA - MEDICINE STORE
4, Tinubu Sqare Lagos

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22878 Nigeria, (Ọja
ATI NI ṢỌBU
IṢẸ-OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN.


# OWE SI OLOTU

## Awa Adibo Ni Yio Pari Ija Na

Olotu, Ngo sọpẹ fun ọ, bi ẹ ba le tete gba mi laye ninu "Irohin Imọlẹ" yin lati sọ wipe, nko ri ọgbọn ati lakaye ninu ipinnu ti Alhaji R. A. Adẹṣina pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni lori ipari ija to mbẹ larin Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ. to mbẹ lọgba ẹwọn pẹlu Oloye Samuel Akintọla, to mbẹ lori Ite Ijọba rẹ. ti nwọn lọ gbe ba Ọba Alaiyeluwa Adesọji Aderemi Ọni Ile-Ifẹ lasiko ti ọjọ ati jade kuro lọgba ẹwọn Awolọwo ku si dẹdẹ.

Ohun ti ọrọ na jọ loju mi ni wipe, Alhaji Adesina ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ nwọn ti sun nwọn ti kan ogiri ati wipe nwọn ti ri i daju wipe lara Ọlọla Awolọwọ di ọkan tọmọde tagba Adibo ti yio dibo fun awọn asoju sile igbimọ apapọ ijọba ilẹ Naijiria to ku si dẹdẹ yi wa

Ati wipe bi nwọn bajẹ ọgbọn pari ija ti o ba fi ọgbọn pari ija ti o ba jẹ wipe awọn lo fi Awolọwọ silẹ ki a to dibo ero ọkan wọn ni wipe boya ọkan awọn adibo yio kuro lara Awolọwọ nipa bẹ awọn Adibo yio le dibo fun ẹgbẹ oselu miran to yatọ si ẹgbẹ UPGA.

A dupẹ lọw nyin, Ẹsẹn Ẹ ku ifẹran ẹ si run ku atunṣe pẹlu. Ohun ti mo fẹ sọ fun Alhaji wa ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni wipe iṣẹ Lade ni ẹ fẹ ṣe. Oluwa yio fun nyin ni Laada, ṣugbọn asiko ipari ija Awolọwọ pẹlu Akintọla ti kọja fun enia kan tabi, enia meji, ẹ jẹki awọn Adibo fi ibo wọn pari ija ki Awolọwọ ati Akintọla le mọ ara ipo ti ẹni kọọkan wọn wa larin ilẹ Naijiria.

Olotu, ẹ sun o.

Ẹru obodo
Eko



Alagba Ẹrukobodo

Bi ero ọkan wọn ko ba ose bẹ Nibo ni Alhaji Adesina ati ẹlẹgbẹ rẹ ti wa lati nkan bi ọdun meji abọ ti ede aiyede na ti bẹ sile ti a ko fi ri Alhaji Adeşina ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ fun ipari ija na titi o fi di asiko yi?

## Ọmọ Ipokia Ko Si Lẹhin Ẹgbẹ Dẹmọ

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati sọ fun Oloye A. B Ashin Boro kini Olori ẹgbẹ Dẹmọ peruawọn ọmọ Ipokia ati agbegbe rẹ ko ṣe ẹgbẹ Dẹmọ Awọn abilero kan npariwo pe gbogbo Ipokio ati agbebe rẹ wa lẹhin ẹgbẹ A. B Ashin. Irọ nla ni nwọn npa fun.

Ko si Olọgbọn kan ni ilẹ Yoruba ti o je fi tinutinu tẹle asiwaju ẹgbẹ Domọnu nitori ẹgbẹ ọdalẹ Parapọ ni Bi ẹnyin ẹgbẹ janduku qa ti lo yọ Ọbẹ ake ada ati ilu siwa, a ko ni kuro ninu ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA)

Mo dupẹ lọwọ awọn asiwaju wa Oloyẹ D. K. Ahansa, Oloye Y. B Abioro Bi ko ba si wọn ni ẹgbẹ Domọnu yio ti le wa koro nni Ipokia Ọpẹ lọpa awọn Oloye wa meji ti o fi ọkan balẹ

Mo bẹ ẹyin ẹgbẹ Ọlọpẹ ati Alakukọ ki ẹ ṣe ọkan ẹyin giri ki eski ọ owo nyin pọ gboingboin emi mọ dajudaju wipe ẹgbẹ Dọmọnu iku ekutelo ma tu ẹfọ rẹ laipẹ tọjọ (UPGA) ti wọle Ẹgbẹ Dọmọnu ati awọn ọrẹ rẹ kole ri wa gbese ẹkan han ninu ibo apapọ ti mbọ yi Ẹyin ọmọ Ipokia ati agbegbe rẹ ẹjẹ ka dibo fun UPGA ki wọn wọle mo bẹ nyin Irọ ni Ashiru npa ka kiri.

Mo dupẹ lọwọ olotu Irohin Imọ ẹ fun aye ti ẹfi gba mi laye na Olu wa Ọba Ogo Ogo ni jẹ ki ẹni aburu aiye Ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o Amin

Emi ni
Yisa Yusuph
IPOKIA

# IGBOMINA ATI EKITI DADA NI TI NYIN

### Lati Ọwọ Samuel Kọlawọle Eko.

Mo ki ẹ n y i n ọmọ Igbominaa ti Ekiti ti nwọn ṣe ipade ni ọjọ Aba-ẹta ti ṣe ọjọ keje oṣu kọkanla ọdun yi ni Ọgba Eletu Iwaṣe ti wọn sọrọ lori awọn ti a yan fun idibo ọduu yi.



Ọgbẹni M. A. Ọlanrewaju

Mo dupẹ lọwọ ẹgbẹ na mo si tun fi iyin fun awọn ọmọ ilẹ Igbomina ati Ekiti wọn ṣe ipade ti wọn si tun ṣọ oko ọrọ lu Ọgbẹni M. A. Ọlarewaju, emi gẹgẹbi ẹnikan gbe awọn ẹgbẹ ti o ṣe ipade na ni ẹhin fun ọrọ wọn pe awọn yan ọgbẹni wa Ọlarewaju si ile Igbimọ Aṣofin ti Eko a t i pe awọn na ni awọn tun sọ wipe awọn ko fẹ mọ a t i pe Paul ọmọdara Dada ni awọn fẹ ni ọdun yi ati wipe ọgbẹni yi na lo le g b a wa la ti iya ko fi ni jẹ wa tọmọtọmọ, ati pe oti da wa loju wipe ẹ i o m i r a n ti lo aye ti ayan si ni ile Igbimọ aṣofin fun ọ d u n mẹwa ti awa ko si ri ka n nunu iwe iroyin kankan tabi ri gbọ wipe Ọgbẹni wa yi bere kini kan fun wa un nkan anfani ilẹ ilu wa. Lẹhin ti adibo f u n Ọgbẹni wa yi tan ti ko ba wa gbọ nkan ti o nse wa ti o bere si gbọ ti ara rẹ ti o tun nwa bere ibo wa, Emi mọ daju wipe ko si ẹni k a n ninu wa ti yio tun jẹ ṣe esi fun ọgbẹni wa yi ni Ibo rẹ ati papa pe mo bẹ ẹnyin enia mi wipe kiẹ jọwọ kiẹ fi Ibo yin rọ ẹlomiran kuro lori aga ti ọ d u n yi kia si fi Ibo wa be ỌMỌDARA DADA wọ'le. Awa na ti gbọn to awa ko si ni ṣe eru ọdun maruu miran si fun ọgbẹni wa mọ.

Mo si fẹ ko ye gbogbo ara mi gbogbo wipe larin ọdun mẹwa ti Ọgbẹni wa yi lọ ni ori aga o yẹ o si tọ wipe ki o ba wa ṣe ọna bi awa yio tiṣe ni oju ọna motor Ọlọda, bẹ na ni osi tọ wipe ki o ba wa ṣe ọna bi ile iwe giga ni ọdọ wa bẹ na ni o yẹ ki a ti ni Omi ẹrọ. Ile Iwosan ati Post Office ati nkan miran bere lo ti Ọgbẹni wa yi ko bikita lati ba wa da imọran rẹ debi ti yio se ọna bi yio ṣe de agbegbe awa adibo rẹ. Kini Ọgbẹni wa yi ṣe f u n awa ti o tun nbere ibo wa ki o tun wa di ọdun mẹdogun re lori aga.

Nitorina mo bẹ ẹnyin enia mi gbogbo wipe Ọgbẹni Mr. P.A.O. Dada ni kiẹ dibo nyin fun ti Ọgbẹni Ọlanrewaju yi ti to gelẹ na ẹ jẹ ki a tun dan Dada wo nitori owo ti enia ṣe fun ọdun mẹwa ti ko gbe enia o yẹ ki a pati ki a si tun wa owo miran ṣe, nitọrina ẹ jẹ ki a tun dan Dada wo o. Gẹgẹbi ẹyiu na ti ṣe mọ wipe PAUL ỌMỌDARA DADA ti a fẹ lati dibo fun yi ati Ọgbeni Ọlanrewaju ọmọ Baba kanna ni gbogbo wọn jẹ. awọn ni ọmọ wa awa si n Baba wọn. Ọlaurewaju jẹ Akobi ọmọ wa asi ti sin debi ti ẹru ko ti le ba mọ tabi ọmọ ti enia ba ti to debi ẹru ko ṣe ni ba mo oje ko ye ki a ton mu ọmọ keji ki a tun to on na debi ti ẹru ko fi ni le ba mọ. Iyẹn ni o jẹ ki a tun gbe Dada sita fun ibo ti ọdun yi ti wipe Ọgbẹni Dada si n o to ẹru wa ru ni le igbimọ aṣofin Naijiria ati papa yi je Olukoni kan pataki ni Bello Unifasiti ni Zkria, bẹni ni o si tun gba oye dada, nitori idi eyi ti a ba ro ọrọ *na* wo dada, nitori idi eyi ti a ba ro ọrọ na wo dada ao ri wipe Ọgbẹni wa yi lo tọ ni pe ti a ba yan sile igbimọ aṣofin yio to ẹru wa ru yio si ma le bere nkan ti a ba nfẹ fun wa laisi ifoiya kankan. Nitori idi eyi mo bẹ gbogbo ẹnyin ara mi gbogbo kiẹ jọwọ kiẹ fi iho yin gbe DADA wọ'le kia si j e r e ẹkọ ti awọn ọmọ wa nọ k ọ l aisi ifoiya tabi Ibẹru.

Inu mi yio dun tiẹ ba le fi ibo nyin yan ọgbẹ ni P. A. O DADA wọ'le igbimọ aṣofin Naijiria ni ọdun yi Ọgbẹni Ọlanrewaju ti dagba to ni ile igbimọ aṣofin ẹjẹ ki a yau ọmọde kekere ti oni igboiya ati jẹ ṣẹ ti a ba ran fun wa.

Mo wa fẹ lati bere lọwọ gbogbo ọmọ ilẹ Igbomina ati Ekiti wipe njẹ gbogbo nkan anfani ti a nri ati eyi ti a ngbọ ni oriṣiriṣi gẹgẹbi ile Iwosan, Ina Onimọnamọna, Titi Ọlọdẹ, p o s u Ofisi (Post Office) ati nkan meremere bẹ yẹn ko tọ si nyin ni? Nfẹ ki Ọgbẹni wa yi tọka si ọkan tio ba ṣe ninu awọn iṣẹ tia ka si oke yi fun awa adibo agbegbe rẹ,

Nitorina kia ma si sọrọ pupọ nitori oro oni i s ọ si ọrọ ti kọja eyi ti enia gbọdọ tun ma sọ le. ẹ j ẹ kia fi Ibo wa wa g b e Ọgbẹni DADA wọ'le hi Ibo ọdun yi.

Emi yio tun masọ e y i tokn fun yin ni ọjọ miran. Ki Oluwa sọ wa di ọjọ miran. Mo dupẹ lọwọ ẹnyin ti feti silẹ fun ti si fi suru ka iwemi yi tiẹ si nfi ọkan ba ọrọ mi yi a lọ.

Olotu mi ọwọn, Ọlọrun ko ni jẹ ki a ṣiṣe, Ọ k ọ Ọba ko ni sa yin lẹsẹ O.

Amin Aṣẹ.


## Adura Jẹ J'ogun Lọ

| | |
|---|---|
| A ti ni Iwe Adura pataki fun Asiki lati Musira | 2/6 |
| Iwe Adura Akanṣe ati apẹrẹ ile aiye | 2/- |
| Iwe Itumọ Ala ati Adura Ala ibanujẹ | 3/6 |
| Iwe Afọmọ-isin Ojiṣẹnia Muhammed | 1/6 |

Bere tabi F'owo ranṣẹ si :—
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
Ni eti Ọja Jankara.

## Kini F. Nduro Fun ?

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen ) asọ oke, Tapẹta Sapẹti ati oriṣiriṣi asọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni iṣeju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ
**JOYCELAUNDRETTESERVICE**
34, Ojo — Oniyun Street,
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ anna. A le wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi iṣẹ wa dara tu
Owo pọọku ni a si ngba.